# ẸṢẸ MIRIAMU ATI AARỌNI

## Numeri 12:1-16

## ẸKỌ 100 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ mã gbọ ti awọn ti nṣe olori nyin, ki ẹ si mã tẹriba fun wọn: nitori nwọn nṣọ ẹṣọ nitori ọkàn nyin, bi awọn ti yio ṣe iṣíro" (Heberu 13:17).**

**I Iṣọtẹ Miriamu ati Aarọni ati Bi Ọlọrun Ti Jà fun Mose**

1. Miriamu pẹlu Aarọni fi ilara sọrọ odi nipa Mose, wọn fi ẹmi ti o wà ninu wọn hàn, eyi ti i ṣe igberaga, ati ifẹkufẹ ipo aṣẹ ti ayé, Numeri 12:1, 2; Owe 25:6, 7; Isaiah 14:12-15; Ọbadiah 4; Matteu 23:12
2. Oluwa gbọ ọrọ igberaga ati ọtẹ wọn, Numeri 12:2; 1 Kronika 28:9; Orin Dafidi 44:21; Jeremiah 17:9, 10
3. Iwa rere Mose paapaa tó lati sọ gbogbo ẹsun wọnyii di ofo, Numeri 12:3; Galatia 5:22, 23; 1 Peteru 3:4; Matteu 5:5; Orin Dafidi 37:10, 11
4. Ọlọrun jẹri iranṣẹ Rẹ, Mose, niwaju awọn olùfisùn, O si sọ fun wọn iru idapọ timọtimọ ti Oun ní pẹlu Mose, ti o ju ti ẹnikẹni lọ lori ilẹ alaaye, Numeri 12:4-8; Orin Dafidi 76:8, 9; Deuteronomi 34:10-12

**II Iya Ẹṣẹ Naa**

5. Ibinu Ọlọrun ràn si awọn ọlọtẹ naa, Numeri 12:9; Amosi 9:2-4
6. Ijiya nla de ba wọn: ẹ̀tẹ̀ bo Miriamu, Aarọni si ni ibinujẹ ọkàn pe ẹ̀ṣẹ awọn mejeeji ni o mú iru itiju yii bá wọn, Numeri 12:10; Lefitiku 13:38-46; Orin Dafidi 75:6, 7
7. Aarọni bẹbẹ fun imularada arabinrin rẹ̀; ati ifiji ẹ̀ṣẹ awọn mejeeji, Numeri 12:11, 12
8. Mose gbadura agbayọri fun iwosan Miriamu, Numeri 12:13; Esekiẹli 33:14-16; Jakọbu 5:14-16
9. Bi a tilẹ wo awọn oluṣe buburu naa sàn, ti a si fi oju rere Ọlọrun gba wọn sipo pada, sibẹ iya miiran kù lori wọn eyi ti o jẹ afọwọfa nipa aiṣedeedee wọn, ki i ṣe nitori titobi ẹ̀ṣẹ wọn nikan ṣugbọn nitori ki wọn le jẹ apẹẹrẹ fun awọn ẹlomiran, Numeri 12:14; Lefitiku 14:1-57
10. Idaduro dé bá ijọ eniyan Ọlọrun ninu irin-ajo wọn si Ilẹ Ileri nitori ẹṣẹ awọn wọnyii ti o ṣọtẹ si alakoso ti Ọlọrun yàn fun wọn, Numeri 12:15, 16; Joṣua 7:10-12; Isaiah 59:12

## ALAYE

**Wolii Ti Kò Ni Ọlá**

Nigba ti iṣọtẹ alainilaari ti awọn Ọmọ Israẹli ṣe ṣẹṣẹ lọ silẹ ti wọn si ṣí kuro ni ibudo wọn ni awọn akọsilẹ ti inu ẹkọ wa yii ṣẹlẹ. Ọpọ igba ni Mose ti gbọ kikun awọn Ọmọ Israẹli lapapọ si oun ati Aarọni ati si Oluwa lori iṣoro ti o ba de. Ṣugbọn atako ti o ba pade ni akoko yii jẹ eyi ti o yatọ ti o si wọ ọ lara pupọ ju lọ eyi ti o dùn ún gidigidi, nitori o ti ọdọ awọn ti o sun mọ ọn, ti o si ṣọwọn fun un, jade wa.

Lati ẹ̀yin ibudo ni iṣọtẹ ati irahun atẹyinwa ti i maa bẹrẹ, laaarin awọn adalu ọpọ eniyan ati awọn ti ko sunmọ Ọlọrun. O ṣe e ṣe ki awọn wọnyii má ri iṣẹ iyanu Ọlọrun ni ọna ti o hàn kedere bi o ti hàn si awọn Ọmọ Israẹli, nitori wọn ki i fi igba gbogbo wá si inu agbo nibi ti agbara Ọlọrun gbe wà. Ko ṣoro lati ri idi rẹ̀ ti awọn wọnyii fi n kùn ninu ọkàn wọn ti wọn si n ráhun bi ohunkohun ba de, ti wọn si n funrugbin ainitẹlọrun si ọkàn awọn ẹlomiran pẹlu. Ko ṣoro lati ri i bi irahun wọn yoo ti gba gbogbo ibudo kan ti yoo si ti dá iṣọtẹ silẹ. Ṣugbọn ọran ti isisiyii ko bẹrẹ lati ẹ̀yin ibudo, bẹẹ ni ki i si ṣe awọn adalu ọpọ eniyan ni o da a silẹ. Ọdọ awọn ti o sunmọ Mose timọtimọ ni o ti bẹrẹ, o bẹrẹ lati ọdọ awọn ẹni ti o dabi ẹni pe wọn fara mọ́ alakoso wọn oloootọ tọkantọkan, ti wọn si jẹ́ alajọru ajaga itọju awọn Ọmọ Israẹli.

Jesu sa ipá Rẹ̀ lati sọ ti ọna iye ainipẹkun fun awọn wọnni laaarin ẹni ti O gbé dagba, awọn ẹlẹgbẹ Rẹ̀ nipa ti ara ki O to bẹrẹ iṣẹ iranṣẹ Rẹ ni gbangba, ṣugbọn bi O ti n sa ipá Rẹ lati ṣe bẹẹ ni O n ri idojukọ. Nigba ti O fi Nasarẹti silẹ O ba wọn wi gidigidi pe "Kò si woli ti o wà laili ọlá, bikoṣe ni ilu ati ni ile on tikararẹ"(Matteu 13:57).

Ohun ti o doju kọ Mose ki i ṣe pe awọn ara ile rẹ kọ̀ lati mọ̀ ati lati jẹwọ pe Ọlọrun ni o yàn án gẹgẹ bi wolii ati alakoso. Miriamu ati Aarọni gba nnkan wọnyii nipa Mose gbọ́, ṣugbọn nitori ẹṣẹ igberaga ti n fi arekereke ṣiṣẹ ti o si n fa iparun, eyi ti a n pè ni ijọ-ara-ẹni-loju, wọ́n wi pe Ọlọrun ni Ó pe awọn naa ti Ó si fi aṣẹ lé wọn lọwọ.

"Ohun gbogbo ti mbẹ li aiye, ifẹkufẹ ara, ati ifẹkufẹ oju, ati irera aiya, ki iṣe ti baba, bikoṣe ti aiye" (1 Johannu 2:16). Owú ati ilara ti o n mu ki awọn eniyan lepa ipò ati igbega ninu ohun ti ara ninu ayé, tabi boya ninu iṣẹ Ọlọrun, jade lati inu irera ti ó wà ninu ọkàn wọn lati gbé ara wọn ga. Ọrọ Jesu ti o wi pe: "Ẹnikẹni ti o ba si gbé ara rẹ̀ ga, li a o rẹ̀ silẹ; ẹnikẹni ti o ba si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ li a o gbé ga" (Matteu 23:12), jẹ idalẹbi fun awọn wọnni ti o jẹ pe lọnakọna ifẹ lati gbé ara wọn ga si ipò ọlá ni o pilẹ ilepa wọn.

**Ojú ti N Ṣọ́ ati Etí ti O Ṣipaya**

Ṣugbọn iwa ati ero awọn ọlọtẹ meji wọnyii kò pamọ́. Ọrọ kekere kan ti ẹni ti kò fara balẹ miiran le ṣai kiyesi wà ninu Bibeli ti o fi ye ni pe Ọlọrun gbọ́ ohun ti wọn sọ. Nigbakigba ti Ọlọrun ba si gbọ ti a n dá awọn iranṣẹ Rẹ̀ ti O fi ororo yàn ti O si fi aṣẹ fun lẹjọ oju Rẹ̀ a maa ri i, Oun a si jẹ ẹnikẹni ti o ba ṣe bẹẹ niya, ki iru ẹni bẹẹ ba le ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ati pe ki orukọ Ọlọrun ki O má ṣe di yẹpẹrẹ tabi ki ẹnikẹni fi ọwọ pa idà Rẹ̀ loju.

"Nitoriti oju OLUWA nlọ siwa sẹhin ni gbogbo aiye, lati fi agbara fun awọn ẹni ọlọkàn pípe si ọdọ rẹ̀" (2 Kronika 16:9); iru agbara ti Ọlọrun yoo fi hàn, yoo mú itiju ati idaamu ba ẹni naa ti o ba dawọ le e lati doju kọ ẹni ti ọkàn rẹ̀ pé si Ọlọrun. A ko le sá kuro niwaju Ọlọrun! O mọ gbogbo ọkàn O si mọ ero ikọkọ ti o wà nibẹ. O n kiyesi gbogbo ohun ti a n ṣe O si n gbọ gbogbo ohun ti a n sọ.

Asán ni gbogbo ero eniyan lati fi ara pamọ fun Ọlọrun ti O n ri ohun gbogbo! Oju ti o gbe Ọrun ri ohun ti o ṣẹlẹ ni Ọgbà Edẹni, ati ẹ̀ṣẹ ti o wà ni ookan aya Adamu ati Efa, le riran tayọ gbogbo ohun ti ẹda gbé kalẹ lati fi ipò ẹṣẹ rẹ pamọ. "A! Oluwa ỌLỌRUN! wò o, iwọ ti o da ọrun on aiye nipa agbara nla rẹ ati ninà apa rẹ: kò si ohun-kohun ti o ṣoro ju fun ọ. . . . . titobi ni igbimọ, ati alagbara ni iṣe; oju rẹ ṣí si gbogbo ọ̀na awọn ọmọ enia: lati fi fun olukuluku gẹgẹ bi ọna rẹ̀ ati gẹgẹ bi eso iṣe rẹ̀" (Jeremiah 32:17, 19).

**Ẹsun naa ati Abajade Rẹ**

Ẹṣẹ a maa ṣe awawi, a si maa fi ohun ti o bojumu ti o si ṣe e gba yẹwo siwaju lati fi bo iwa buburu rẹ laṣiri. Nihin, ẹṣẹ ti o wà nidi ọran yii ni igberaga, ijọ-ara-ẹni loju, iṣọtẹ ati ainitẹriba. Ṣugbọn ẹsun ti wọn kọ́ fi siwaju yatọ si gbogbo iwọnyi, ṣugbọn wọn sọrọ nipa aya ti Mose fẹ́. Ẹsun ti ko ni laari yii ni wọn fi ṣe bojuboju fun iṣọtẹ wọn, ṣugbọn owu ati igberaga ti o wà lọkan awọn ọlọtẹ ni o pilẹ aile tẹriba wọn. Wọn fẹ agbara ati iyi ti aye ti wọn ro pe yoo jẹ ti ẹnikẹni ti o ba jẹ alakoso orilẹ-ede nla bi ti Israẹli.

Ko si ohun ti o le tete dá ede-ko-yede silẹ laaarin ọmọ eniyan bi owu ati ilara fun ipò, agbára ati ọlá. Ifẹ atọkanwa, ọla, inu didun, ere, ojuṣe ati aabo lai mẹnu kan ikiya ati ojurere ti Ọlọrun n fi han fun awọn ti o bẹru Rẹ̀ ni awọn eniyan maa n ṣe aibikita fun nigba ti wọn ba n lepa ògo asán, ipá ati agbara lati di alakoso. Ohun ti o ṣẹlẹ yii fi han pe awa tikara wa ní lati yẹ ọkàn wa wò, nitori bi eniyan ti o ni iru ipo, anfaani ati ipe bi ti Miriamu ati Aarọni ba le ṣubu si iru ẹṣẹ yii, a ko le gba ara làyè lati fi ọkàn wa balẹ pe a ko le bọ́ sinu idanwo bẹẹ.

Awọn kan gbagbọ pe Miriamu ni o dá rugudu naa silẹ nitori orukọ rẹ̀ ni a kọ́ dá ati pe oun nikan ni arun ẹtẹ ba le. Awọn ẹlomiran wi pe Aarọni ti o ti fi han pe oun jẹ́ alai-ṣoro-tẹ̀ ati ẹni ti ero rẹ̀ ko duro ṣinṣin nibi kan ni arabinrin rẹ̀ ṣì lọna sinu ẹṣẹ ti o mu abuku ba orukọ awọn mejeeji. A mọ daju pe awọn mejeeji ni Ọlọrun binu si, nitori naa a mọ pe awọn mejeeji ni o jẹbi niwaju Rẹ̀. Arun ti ko gboogun ti o buru ti o si lẹru, ti ẹni ti o ba n ṣe ko gbọdọ gbe laaarin awọn olufẹ ati ọrẹ rẹ̀ bà lé Miriamu. Ṣugbọn Aarọni ko lọ lai fi ara gbá ijiya rara.

Ifẹ ará ti o wa laaarin idile Amramu ati Jokebedi ko kere. Miriamu yii, nigba ti o wà lọmọde ni o ti duro ninu oorun gbigbona janjan ti Egipti lati maa ṣọ́ apoti èsú ti a gbé aburo rẹ̀, Mose, ìkókó sí, ẹni ti o yẹ ki a ti pa, ṣugbọn ti awọn obi rẹ̀ dá sí. Lẹyin ti ọmọbinrin Farao rí apoti naa, Miriamu lọ ba a, o si fi ọgbọ́n rọ̀ ọ́ lati gba alabatọ fun ọmọ naa lara awọn obinrin Heberu lati tọju ọmọ naa titi yoo fi di gende. Oun naa ni o dá orin ègbè fun awọn obinrin Israẹli ni idahunsi orin Mose nigba ti wọn la Okun Pupa kọja. O ti duro ti arakunrin rẹ̀, ni ọpọlọpọ igba, ninu iṣoro ati wahala nigba ti o dabi ẹni pe ireti ko si mọ ni titẹle ọna Ọlọrun.

Aarọni pẹlu ti fi iwa ti o wú ni lori hàn bi o tilẹ jẹ pe o jẹ alailera. O ti fara mọ Ọlọrun to bẹẹ gẹẹ ti ó le gbọ́ ohùn jẹjẹ Ọlọrun ti O pe è kuro ninu ifọkanbalẹ Egipti lati lọ si irin ajo ogunlọgọ mile, ni aarin aginju ti ko mọ ri, lati lọ pade Mose, lọna ti o kọja oye eniyan, nitori ko ri i tabi gburo rẹ lati nnkan bi ogoji ọdun sẹyin gẹgẹ bi a ti sọ fun ni. Ọlọrun fọkan tan an lati ṣe iṣẹ pataki nipa kikede aṣẹ Rẹ̀ ọrun ni aafin Farao, ọba onroro ni. O ni ẹbun nipa ti ara ati nipa ti ẹmi ti Ọlọrun mọ̀ pe Oun le ṣakoso ki O si mu lo gẹgẹ bi O ba ti fẹ. Lakotan, Aarọni jẹ́ apẹẹrẹ Alagbawi ti yoo kó gbogbo ẹbẹ ẹlẹṣẹ ti o ba ronupiwada lọ siwaju Itẹ Idajọ Nla nì ti yoo bẹbẹ fun idasilẹ rẹ̀, lẹyin ti o ti fi Ẹjẹ alailẹṣẹ ara Rẹ̀ ra idariji fun un.

Dajudaju ko ṣẹṣẹ di igba ti Ọlọrun ba kọ lu Aarọni pẹlu arun ti ko ni jẹ ki o wulo fun iṣẹ ti a pe e si ki O to le jẹ ẹ niya. Oju ti o tilẹ fi n wo arabinrin ti o fẹran ti arun buburu ti n ràn, ti o si n jẹ ẹran-ara run bayii kọlu, ati oye yii pe, gẹgẹ bi ipò rẹ̀, oun ni o gbọdọ sọ fun un pe ki o jade kuro laaarin ibudo Israẹli titi lae, jẹ ijiya ti o wuwo. Nigba pupọ, o maa n ṣoro pupọ lati farada riri olufẹ kan ninu irora ju lati farada irora naa gan an. Igba melomelo ni a maa n gbọ ti ẹni ti ara rẹ̀ le maa n gbadura pe ki a gbe irora olufẹ ti o n wò sara oun, nitori ara rẹ̀ ko gba a lati maa wo olufẹ rẹ̀ bi o ti wà ninu irora tabi ipọnju.

**Idalare ti Ọlọrun ati Ẹsun Eniyan**

Ẹri ti o ga ju lọ lati fi han pe Mose ni o wà ni ipò iṣẹ-iranṣẹ ti o ga ju ti ẹnikẹni lọ ni igba ayé rẹ̀ fara han nitori idojukọ yii. Ohun ti o ṣẹlẹ yii jẹ itunu fun awọn wọnni ti a n sùn ni ẹsun eke. Bi awọn naa ba gbe ẹmi suuru ti ki i gbeja ara rẹ̀ wọ̀ gẹgẹ bi Mose ti ṣe, Ọlọrun yoo jà fun wọn. Bakan naa ni eyi jẹ ikilọ fun awọn wọnni ti yoo gba agbara eṣu láyè lati mú wọn lò nipa ilara ninu ero ati ọrọ ẹnu wọn. Ọlọrun n gbọ ọrọ ti wọn n sọ, O si mọ ero ọkàn wọn. Ni ọjọ kan Oun yoo rán idajọ Rẹ̀ ti o daju si wọn ni airo tẹlẹ.

Awọn alatako Bibeli ti ko gba Ọlọrun gbọ sọ fun ni pe, akọsilẹ naa pe, Mose jẹ oninu-tutu fi hàn gbangba pe ki i ṣe nipa imisi Ọlọrun ni a fi kọ Bibeli. Wọn wi pe bi o ba jẹ pe Mose ni o kọ Iwe Numeri, ko ni kọ akọsilẹ yii nipa ara rẹ̀, nitori bi a ti kọ ọ silẹ fi han pe oun ki i ṣe oninu-tutu. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ohun ti o ṣoro loju ẹnikẹni ti o ba gbagbọ. Ọrọ yii ko jade lati gbe iyin ara rẹ̀ kalẹ nipa imisi ẹran ara. Otitọ yii jade lati fi iwa aye rẹ̀ han fun ni lọna ti o le mu ki ẹkọ naa yé ni yekeyeke. Ki i ṣe ifẹ-ara ni o fa a, ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun ni o mí sí Mose ti o si ṣe akoso rẹ̀ nigba ti o n kọ awọn iwe ologo wọnni.

Igba melomelo ni Mose ti jà lati gbé ọlá Ọlọrun ga ju lati wá okiki ati ogo fun ara rẹ̀! Nigba kan anfaani ṣí silẹ fun un lati di orilẹ-ede nla nigba ti Ọlọrun pinnu lati pa orilẹ-ede Israẹli run patapata. Oun i ba ti kọ̀ lati bẹbẹ fun awọn eniyan yii bi i ti maa ṣe nigba pupọ nipa awẹ ati adura titi okun ko ni fi si fun un mọ nigba miiran, oun i ba si ti ri i ti idajọ Ọlọrun yoo sọkalẹ sori awọn alaimoore eniyan ti o n kùn ti o si n ráhùn wọnyii. Nigba pupọ ni o fi han pe oun jẹ́ oluṣọ-agutan tootọ fun ile Israẹli. Nigba pupọ ni o fi han pẹlu pe ohun ti o jẹ ẹ lọkan ju lọ ni lati ri i pe a bu ọla fun Ọlọrun a si bọwọ fun Orukọ Mimọ́ Rẹ̀. Oninu-tutu tootọ ni oun i ṣe! Onirẹlẹ tootọ si ni pẹlu! Alakoso ati onilaja tootọ ni bakan naa! Oun ni wolii ti o jẹ́ apẹẹrẹ Wolii miiran, ẹni ti O de nigba ti akoko kikun naa de ati Ẹni ti Ọlọrun lati oke Ọrun giga jẹri Rẹ̀ ni Oke Ipalarada pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe.

Ohun ti o ṣẹlẹ ninu akọsilẹ nipa irin-ajo ninu aginju yii kọ́ wa lẹkọọ iyebiye yii pe, bi awọn "Miriamu" tabi "Aarọni" ode-oni ba gba eso buburu ti owú ati ilara láyè lati yọ́ wọ inu ọkàn wọn, o le fi gbongbo mulẹ, yoo si mu wọn gbé ohùn wọn soke lati sọrọ odi si ọkunrin tabi obinrin wọnni ti Ọlọrun ti fi pẹlẹpẹlẹ pe ti O si fororo yàn. Ki Ọlọrun gbà wá lọwọ iṣẹ ọtẹ ti ẹ̀ṣẹ buburu yii n ṣe!

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni orukọ aya Mose?
2. Darukọ baba, iya, arabinrin ati arakunrin Mose.
3. Ki ni ẹsun ekinni ti a fi Mose sùn?
4. Ki ni ẹsun naa gan an ti a fi i sùn nikẹyin?
5. Ta ni a le pè ni olori awọn ti o dá rugudu yii silẹ?
6. Ka ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun pataki ti o sọ nipa iwa Mose, eniyan Ọlọrun, ninu ẹkọ wa yii si ori.
7. Ka awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun miiran si ori ti o sọ nipa ere ti yoo jẹ ti awọn ti o ba ni iru iwa rere nì ti a ri ninu Mose lọpọlọpọ.
8. Ki ni iyatọ ti o wà ninu iran ti a fi han fun Mose ati awọn ẹlomiran ti o tun sọtẹlẹ ni orukọ Ọlọrun?
9. Iru iha wo ni Ọlọrun kọ si awọn ọlọtẹ wọnni?
10. Bawo ni a ṣe jẹ wọn niya nitori ẹ̀ṣẹ yii?